6. Yẹ́ra fún òtútù àti ooru púpọ̀jù kí o má sì ṣí ara sí atẹ́gùn-tútù àti òjò
7. Yẹ́ra fún àwọn ohun tó níí ṣe pẹ̀lú ipá àti agbára.
8. Máa tẹ̀lé ìmọ̀ràn dókítà rẹ
9. Wá ìwọ̀sàn ọgán ní kété tí ààrẹ bá ti wọ̀ ọ́ lára
10. Máa mú omi púpọ̀
11. Má a mu oògùn folic acid kan ní ojoojúmọ́
12. Lọ sí ilé-ìwòsàn àwọn alárùn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ tó bá sún mọ́ ọn jùlọ
13. Dara pọ̀ mọ́ Ẹgbẹ́ Alárùn Sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ kí o sì máa lọ sí ìpàdé wọn lóòrèkóòrè

## KÍ NI OHUN TÍ ÀWỌN ÈTÒ TÓ DÁ LÓRÍ ÀRÙN SẸ̀JẸ̀DỌ̀LẸ LE ṢE LÁTI DOJÚKỌ ÀRÙN NÁÀ?

1. A lè ràn wọ́n lọ́wọ́ láti jẹ kí wọ́n ní ẹ̀mí-gígùn, a sì tún le dín iyé àrùn àti ìṣòrò tí wọ́n le máa ní kù nípa ṣíṣe àyẹ̀wò àrùn Sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ fún gbogbo àwọn ọmọ tuntun ní kété tí wọ́n bá ti bí wọn sílẹ̀, tí ó bá sì jẹ́ pé a rí àrùn yìí lára wọn, kí a máa gba àwọn òbí wọn nímọ̀ràn nípa àwọn ìtọ́jú tó yẹ fún àwọn ọmọ wọ̀nyìí láti ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀.
2. A lè dín ìrora àwọn alárùn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ àti ti àwọn òbí wọn kù nípa gbígbà wọ́n nímọ̀ràn tó kájúà lórí àwọn àrùn àjogúnbá àti pípèsè ìtọ́jú tó kúnjú ìwọ̀n fún gbogbo mùtúmùwà.
3. A lé jára mọ́ ìwádìí láti le wá àwọn oògùn tó le dènà tàbí mú kí ààrẹ tó máa ń ṣe àwọn alárùn ṣẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ dín kù
4. Ìdàsílẹ̀ àwọn ibùdó àrùn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ fún ìgbéláruge àti ìṣètò ìgbaninímọ̀ràn, àyẹ̀wò, ìtọ́jú tó péye, ẹ̀kọ́ ètò ìlera, ìwádìí àti ìkọ́ni lórí àrùn yìí ṣe pàtàkì fún àṣeyọrí àwọn èròngbà (1) àti (3) tí a kọ sókè.
5. A lé rí i dájú pé ìfidípò ọ̀pá-igi hóró ẹ̀jẹ̀ wà ní àrọ́wọ́tó tí owó rẹ̀ kò sì ní gara fún àwọn tó bá nífẹ̀ẹ́ sí i.

## KÍ NI DÍẸ̀ LÁRA ÀWỌN ÈTÒ TÍ Ó WÀ NÍLẸ̀ FÚN ALÁRÙN ṢẸ̀JẸ̀DỌ̀LẸ?

Ní agbègbè Èkó, àwọn Ilé-ìtọ́jú Àrùn Sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ wà ní:

- Ilé-ìwòsàn Ìkọ́ni Fásitì Ìjọba Apapọ̀ tó wà ní Èkó (LUTH),
- Ilé-ìwòsàn Ìkọ́ni Fásitì Ìjọba Ìpínlẹ̀ Èkó (LASUTH)
- Àwọn Ilé-ìwòsàn Ijọba Ìpínlẹ̀ ní Èkó àti Gbàgádà
- Ilé-ìwòsàn àwọn Ọmọdé ní Ọ̀pópónà Massey

Ní ìlú mìíràn yàtọ̀ sí Èkó, kàn sí ilé-ìwòsàn ìkọ́ni tàbí ilé-ìwòsàn alákànṣe ti ìjọba ìpínlẹ̀. Àwọn ètò yìí sì ń gbèèrú síi ni. Fún àlàyé kíkún, kàn sí Àjọ tó ń rí sí Ìtọ́jú Àrùn Sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ ti Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà (Sickle Cell Foundation Nigeria) tàbí Àwọn Ẹgbẹ́ tó ń rí sí Àrùn Ṣẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ ní àdúgbò rẹ.

## KÍ NI ÀWỌN ÈTÒ TÓ WÀ NÍLẸ̀ NÍ ÀJỌ TÓ Ń RÍ SÍ ÌTỌ́JÚ ÀRÙN SẸ̀JẸ̀DỌ̀LẸ TI ORÍLẸ̀-ÈDÈ NÀÌJÍRÍÀ (SICKLE CELL FOUNDATION NIGERIA)?

1. Ìmọ̀ràn tó dá lórí ìjogún àrùn fún àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn àti àwọn olùtọ́jú aláìsàn, àti ìmọ̀ràn ìṣáájú-ìgbéyàwó fún àwọn alárùn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ.
2. Yàrá àyẹ̀wò hóró ẹ̀jẹ̀
3. Ètò ìpàárọ̀ ẹ̀jẹ̀ alájàáàbalẹ̀.
4. Ètò àyẹ̀wò fún àwọn olóyún tó jẹ́ alárùn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ.
5. Ìtọ́jú ọgbẹ́ ẹsẹ̀.
6. Ètò ìdènà àrùn rọpárọsẹ̀ fún àwọn ọmọdé tó ní àrùn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ (ọdún méjì sí ọdún mẹ́rìndínlógún)

## KÍ NI ÀWỌN OHUN TÍ O LÈ ṢE LÁTI RAN ẸNI TÓ NÍ ÀRÙN SẸ̀JẸ̀DỌ̀LẸ LỌ́WỌ́ NÍ ÀGBÈGBÈ RẸ?

1. Pèsè owó fún ìwòsàn, ìtọ́jú àti ìgbáyégbádùn ẹni tó ní àrùn yìí.
2. Dara pọ̀ mọ́ ẹgbẹ́ tó ń rí sí ìtọ́jú àwọn alárùn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ ní agbègbè rẹ kí ọ̀rọ̀ ẹgbẹ́ náà sì múmú láyà rẹ dáadáa.
3. Ràn wá lọ́wọ́ láti dá Ẹgbẹ́ tó ń rí sí ìtọ́jú àwọn alárùn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ ní agbègbè tàbí ní ilé-ẹ̀kọ́ rẹ sílẹ̀.

**SICKLE CELL FOUNDATION NIGERIA**
"Bringing Hope to the African Child"

## ÀWỌN TÍ O LÈ KÀN SÍ


Àjọ tó ń rí sí Ìtọ́jú Àrùn Sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ ní Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà
(Sickle Cell Foundation Nigeria)
Àdírẹ́sì: Ibùdó Ìtọ́jú Àrùn Sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ
(National Sickle Cell Center) ní Ìdojúkọ LUTH,
Idi-Araba, Surulere, Ìpínlẹ̀ Èkó
Tel: +2348035846666, +2348100002003
Email: info@sicklecellfoundation.com
Website: www.sicklecellfoundation.com
Sickle Cell Foundation Nigeria
Sicklecellnig
@Sicklecellfoundationng



With the support of




# ÀRÙN SẸ̀JẸ̀DỌ̀LẸ

## ÀWỌN KÓKÓ PÀTÀKÌ

**SICKLE CELL FOUNDATION NIGERIA**
"Bringing Hope to the African Child"

# ÀWỌN KÓKÓ PÀTÀKÌ



## KÍ NI ÀRÙN SỆJẸ̀DỌ̀LẸ?

Àrun sẹ̀jẹ̀dọ̀le jẹ́ àmodi àjogúnbá inú ẹ̀jẹ̀ tí kò ní ìwòsàn tí ó sì máa ń dín agbára hóró ẹ̀jẹ̀ kù, ó máa ń fa ara-ríro lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan àti àwọn àrun-burúkú tó máa ń ránni nígbà èwè. Kí èèyàn tó le ní àrùn yìí, ẹni náà yóò ti jogún abàmì hóró ẹ̀jẹ̀ tó dà bíi ọ̀kọ̀ tí wọ́n fi ǹ ká èsò orí-igi láti ọ̀dọ̀ àwọn òbí méjèèjì. Ní èdè kúkúrú, abàmì hóró-ẹ̀jẹ̀ yìí ni a mọ̀ sí Hb S, lẹ́yìn tí ọmọ bá jogún rẹ̀ tán, ọmọ náà yóò padà wá ní ohun tí a mọ̀ sí HbSS. Hóró ẹ̀jẹ̀ tí ó dá pé ni a mọ̀ sí Hb A.

## KÍ NI HÓRÓ ẸJẸ̀?

Hóró ẹ̀jẹ̀ tàbí Hb, ní èdè kúkúrú, ni ohun-èlò aláwọ̀ pupa tí ó wà nínú ẹ̀jẹ̀. Iṣẹ́ rẹ̀ ni láti máa gbé afẹ́fẹ́ àmísínú láti inú ẹ̀dọ̀-fóró lọ sí oríkèèríkèé àgọ́ ara wa.

## KÍ NI ÀÌTÓ-ẸJẸ̀?

Àìtó-ẹ̀jẹ̀ túmọ̀ sí kí hóró ẹ̀jẹ̀ má tó bó ṣe yẹ kó tó nínú ara. Nípa báyìí, ẹ̀jẹ̀ kò ní ní agbára láti le gbé afẹ́fẹ́ àmísínú tó yẹ kó gbé. Ìyárakọ̀ṣẹ́sílẹ̀ Hb S ni ó máa ń ṣokùnfa àìtó-ẹ̀jẹ̀ fún àwọn tí ó ní àrùn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ. Okùnfà rẹ̀ kì í ṣe nítorí àìtó èròjà áyóọ̀nù, kò sí nílò ìtọ́jú pẹ̀lú oògùn elérọ̀jà áyóònù tàbí oògùn ẹ̀jẹ̀. Ẹ̀yí le pa aláìsàn bẹ́ẹ̀ lára.

## KÍ NI AFARASIN ÀRÙN SỆJẸ̀DỌ̀LẸ?

Afarasin àrùn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ máa ń wáyé lára ẹni tó jogún abala ẹ̀yọ́-ìran tí kò dá pé kan (tàbí ẹ̀so) ti Hb S láti ara ọ̀kan nínú àwọn òbí, tí ó sì tún jogún Hb A láti ara òbí kejì. Irú ẹni báyìí máa wá ní ohun tí a mọ̀ sí Hb AS. Àmì àrùn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ kò ní fojúhàn nínú irú ẹni bẹ́ẹ̀ ṣùgbọ́n ó jẹ́ ẹni tó le kó Hb S ran àwọn ọmọ rẹ̀. Ìfarahàn Hb A tó dá pé nínú ẹ̀jẹ̀ ẹni yìí máa bo agbára àti àtúbọ̀tán Hb S mọ́lẹ̀, nípa báyìí, kò ní ní àrùn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ. Irú ẹni yìí (ẹni tí àmí àrùn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ farasin lára rẹ̀ ṣùgbọ́n tó le fún ẹlòmíràn ní Hb S) máa ń ní ìlera pípé, wọn kò nílò ìtọ́jú kankan, wọn a sì máa gbé ìgbé-ayé àlàáfíà. Ọ̀kan nínú ọmọ Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà mẹ́rin (ìdá mẹ́ẹ̀ẹ́dọ́gbọ̀n nínú ìdá ọgọ́rùn-ún) ló ní Afarasin àrùn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ–Hb AS. Láti mọ̀ bóyá ènìyàn ní àrùn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ (SS), tàbí bóyá ẹ̀nìyàn kò ní (AA), ó ṣe pàtàkì láti ṣe àyẹ̀wò ẹ̀jẹ̀ ní yàrá àyẹ̀wo.

## ǸJẸ́ ÀWỌN ABÀMÌ TÀBÍ IRÚFẸ́ HÓRÓ ẸJẸ̀ MÌÍRÀN WÀ BÍ?

Bẹ́ẹ̀ ni, wọ́n pọ̀ pẹ̀lú, ṣùgbọ́n Hb S ni ó gbajúmọ̀ káàkiri àgbáyé. Hóró ẹ̀jẹ̀ mìíràn tó tún gbajúmọ̀ tẹ̀lé Hb S ní ilẹ̀ Áfíríkà ni a mọ̀ sí Hb C. Apá Aríwá Orílẹ̀-èdè Ghana àti Orílẹ̀-èdè Burkina Faso ni ó ti kọ́kọ́ fojúhàn. Ènìyàn kan nínú àwọn ènìyàn márùn-ùn (ìdá ogún nínú ìdá ọgọ́rùn-ún) láàrin àwọn ara ìlú wọ̀nyí ni ó ní ẹ̀yọ́-ìran C (ẹ̀yí nnì ìfarasin ti hóró C). Ẹ̀yí túmọ̀ sí pé wọ́n ní hóró ẹ̀jẹ̀ Hb AC. A tún le rí Hb C yìí ní Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà pàápàá júlọ̀ ní agbègbè Ìwọ̀-oòrùn Nàìjíríà àti ní ààrín àwọn aláwọ̀ dúdú Ilẹ̀ America, Europe àti ní Caribbean.

Àwọn ènìyàn kọ̀ọ̀kan ní àwọn agbègbè tí a ti mẹ́nubà wọ̀nyí máa ń ní abàmì hóró ẹ̀jẹ̀ Hb SC nípa pé wọ́n jogún Hb S láti ara òbí kìíní tí wọ́n sì jogún Hb C láti ara òbí kejì. Àwọn ìfarahàn àmì hóró Hb SC nínú ẹ̀jẹ̀ jọ ti Hb SS ṣùgbọ́n kì í jà lóòrèkóòrè, kò sì burú bíi ti Hb SS. Àrùn ṣẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ náà ni orúkọ tí a ń lò fún ẹni tó ní yàlá Hb SS, Hb SC tàbí Hb S–betathalassaemia (SBthal).

## BÁWO NI ÀRÙN SỆJẸ̀DỌ̀LẸ ṢE GBILẸ̀ TÓ NÍ ORÍLẸ̀-ÈDÈ NÀÌJÍRÍÀ?

Àrùn yìí pọ̀ gidi. Nǹkan bíi ìdá méjì nínú ìdá ọmọ ọgọ́rùn-ún tí àwọn obí Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà bí ni ó le ní Hb SS. Pípọ̀ tí a pọ̀ ní orílẹ̀-èdè yìí ni ó fà á tí ó fi jẹ́ pé àwa ni a ní àwọn tó ní àrùn yìí jùlọ ní gbogbo àgbáńlá ayé.

## KÍ NI ÀWỌN ÀMÌ TÍ Ó MÁA Ń FI HÀN PÉ ÈNÌYÀN NÍ ÀRÙN SỆJẸ̀DỌ̀LẸ?

Ní ọpọ̀ ìgbà, àmì kankan kì í fojú hàn ní ààrín oṣù mẹ́fà tí ọmọ bá kọ́kọ́ délẹ̀ ayé. Lẹ́yìn ìgbà yìí, ojú yóò bẹ̀rẹ̀ sí ní pọ́n rẹ́súrẹ́sú (Ìbà apọ́njú). Egungun-ríro, inú-rírun tàbi inú-wíwú. Ọwọ́-wíwú, ọwọ́-ríro àti ẹsẹ̀-ríro láàrin àwọn ọmọdé. Ibà, àyà-dídùn àti mímí gbúlegbúle. Àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ìrora a máa wọ́pọ̀ nígbà òjò tàbí nígbà otútù. Bí ojọ́-orí ọmọ náà ṣe ń dàgbà, ó le kéré sí ojọ́-orí rẹ̀, àwọn àmì tí ó ń fi hàn pé ọmọ ti bàlágà kò ní tètè fojúhàn, fún ọmọbìnrin, ó le má tètè bẹ̀rẹ̀ nǹkan-oṣù.

Lẹ́yìnọ̀rẹ̀yìn, ìdàgbàsókè pípé nínú àgọ́-ara máa wáyé nígbà tí wọ́n bá ń gbẹ́nu lé ogún ọdún. Oúnjẹ aṣaralóore máa túbọ̀ ran ìdàgbàsókè lọ́wọ́. Láàrin àwọn ọ̀dọ́ tí wọn kò tíì pé ogún ọdún ṣùgbọ́n tí wọ́n ti kọjá ọdún méjìlá, àti láàrin àwọn àgbàlagbà, ìrọra kì í sábà wọ́pọ̀ ṣùgbọ́n ọgbẹ́ ẹsẹ̀ ní àyíká kókósẹ̀ le máa wáyé. Àwọn aláìsàn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ wọ̀nyí kì í le kópa nínú àwọn eré ìdárayá tó nílò ipá àti agbára nítorí àìtó-ẹ̀jẹ̀ tó ń bá wọn fínra.

Ẹ dákun, ó yẹ kí ẹ mọ̀ pé kì í ṣe gbogbo àwọn alárùn yìí ni wọ́n máa ń ní àwọn àmì tí a kà sókè wọ̀nyí. Àwọn àmì àrùn yìí kì í tiẹ̀ fojúhàn lára àwọn mìíràn títí dìgbà tí wọ́n fi máa gbẹ́nu lé ogún ọdún tàbí títí ìgbà tí irú ẹni bẹ́ẹ̀ bá lọ ṣe àyẹ̀wò ẹ̀jẹ̀. Ara àwọn mìíràn a máa ya gágá fún ìgbà pípẹ́ wọn kì í sí nífẹ̀ẹ́ sí kí àwọn ènìyàn máa káàánú àwọn. Wọ́n máa n fi hàn pé àwọn dá pé àti pé àwọn ní ọpọlọ-pípé bí àwọn tí kò ní àrùn yìí.

## BÁWO NI ÀWỌN ALÁÌSÀN SỆJẸ̀DỌ̀LẸ ṢE RÍ AYÉ SÍ?

Ìwòsàn pípé àti ìtọ́jú àyíká, ìmọ́tótó ara, ìdènà àrùn-kíkó, jíjẹ àwọn oúnjẹ aṣaralóore àti wíwá ìwòsàn fún àwọn àrùn ní kíákíá, tí mú kó ṣe é ṣe fún ọ̀pọ̀ àwọn ọmọ tó ní àrùn sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ láti ye àrùn náà pẹ̀lú ẹ̀mí-gígùn tí wọ́n sì ń gbé ìgbé-ayé ìdùnnú. Nígbà tí ọmọ bá wà ní ilé-ẹ̀kọ́, igbé-ayé tí kò ní ìṣòro ni yóò máa gbé. Ọpọlọ rẹ̀ máa jí pépé, yóò sì máa ta yọ nínú ẹ̀kọ́ rẹ̀.

Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, wọ́n máa ń yege nínú iṣẹ́ wọn ní ọ̀nà tí wọ́n bá yàn láàyò àti ní àwọn ọ̀nà mìíran. Ó máa jẹ́ ohun ọlọ́gbọn láti yàgò fún àwọn iṣẹ́ tó nílò ipá àti agbára ní ṣíṣe. Wọ́n le ní àfojúsùn ìgbéyàwó-ṣíṣe àti ọmọ-bíbí. Ohun tó dára jù ni fún àwọn tó bá jẹ́ obìnrin láti dín ewu tó rọ̀ mọ́ ọmọ-bíbí kù nípa pé kí wọ́n má bí ju ọmọ méjì lọ. Kí wọ́n kàn sí dókítà wọn tàbí Àjọ tó ń rí sí Ìtọ́jú Àrùn Sẹ̀jẹ̀dọ̀lẹ ti Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà (Sickle Cell Foundation Nigeria) fún àlàyé nípa níní ànfàní sí àwọn ètò ìfètò-sọ́mọ-bíbí.

## KÍ NI ÀWỌN ÌṢORO KỌ̀Ọ̀KAN TÓ LE TI ÌDÍ ÀRÙN YÌÍ JÁDE?

Bí ó ti lẹ̀ jẹ́ pé wọ́n le gbé ìgbé-ayé gidi pẹ̀lú ẹ̀mí-gígun, àwọn ìṣòro bíi egungun-ríro, àrùn rọpárọsẹ̀, kíkó-àrùn láti ibòmíràn, àìtó-ẹ̀jẹ̀ pàápàá júlọ lára ọmọ-ọwọ́ tàbí lára àwọn ewe, le já sí ikú àìtọ́jọ́ tí wọ́n ò bá dènà tàbí kí wọ́n tètè wá ìwòsàn to yẹ sí wọn.

## KÍ NI ÀWỌN OHUN TÍ A LE ṢE LÁTI DÈNÀ ÀWỌN ÀÌSÀN TÓ MÁA Ń ṢENI NÍPA ÀRÙN SỆJẸ̀DỌ̀LẸ?

1. Rí i dájú pé àyíká rẹ mọ́ tónítóní nígbà gbogbo
2. Rí i dájú pé o ní ìmọ́tótó pípé fún ara rẹ
3. Dáàbò bo ara rẹ lọ́wọ́ ẹ̀fọn
4. Máa lo àwọn oògùn tó máa ń dènà àrùn ibà gẹ́gẹ́ bí dókíta bá ṣe sọ pé kí o máa lò wọ́n.
5. Dáàbò bo ara rẹ lọ́wọ́ àwọn àìsàn tí a lè kó láti ibòmíràn

